**COVID-19 RESPONSE**

# COVID-19: ALAYE ATI ONA TI A FI'N D'ENA RE

## KINI A N PE NI ARUN COVID-19?

COVID-19 jẹ ajakale arun atẹgun titun ti o ran nipasẹ kokoro aifojuri ti a npe ni corona. O bẹrẹ ni Orile Ede China ati pe o ti tan kale si ọpọlọpọ awọn orilẹ-ede agbaye pẹlu Nigeria.



## KINI AWON AMI IFARAHAN COVID-19?

### Awon olori ami ifarahan ni: ajakale arun tabi otutu ti o buru gan

- Iba (Ara gbigbona)
- Iko
- iṣoro lati mi tabi aile mi dele ati aya di dun



### Apeere pe aisan yi buru tabi o gboji gaan

Bii eniyan merin ninu marun ti o ba ni arun COVID-19 ni o le maa ni ami aisan kankan a bi ki won ni ami aisan ti ko lagbara. Aisan naa maa nlẹ lọpọlọpọ laarin awọn agbalagba (bii awon ti ojo ori won to ọgọta odun abi ju bẹ lọ) ati awon eniyan ti o ni ailera ti o ti pe ni ago ara wọn; fun apẹẹrẹ aisan edo fooro, àtọgbẹ tabi ito suga, jejere, kokoro HIV, ati ikọ-fee.





### Bawo ni o se n ran / tan?

COVID-19 tan lati eniyan kan si ekeji ti eni ti o ba ni aisan naa ba sin tabi wukọ si ara elomiran tabi layikaa rẹ. Fifọwọkanohun ti ẹni  ti o ba ni aisan naa ba wukọ tabi sin si, ti eninaa si mu ọwọnaa lọ si ẹnu, imu tabi oju ara rẹ.









### Ona wo ni ale fi d'ena rẹ ni ayika wa?

1. Wẹ ọwọ rẹ nigba gbogbo pẹlu ọṣẹ ati omi fun ọkere ju lọ, ogun iseju aaya
2. Ti ọṣẹ ati omi ko basi la kokonaa, lo oogun  apa kọkọrọ ọwọ (*hand sanitizer*) ti o ni iwon ogofa (60%) oti ti ko mimu lati fi fo owo.
3. Ya go fun bi bo ara eni lọwọ ati ifi ara ko ara
4. Ya go fun fi fọwọ ti a o fo kan oju, imu ati ẹnu rẹ lọwọ ọwọ
5. Bo ẹnu ati imu rẹ pẹlu igunpa re ti o ba n sin tabi wuko. O si le wuko tabi ki o sin sinu beba fele fele ki o si so nu lesekese.
6. Maṣe fi ọwọ kan igunpa tabi asọ elomiran lai nidi.
7. Jin na si enikeni ti o nwuko tabi to sin, ki o si jina si gbogbo eniyan fun bi 'mita' meji o kere ju.
8. Ti o ba un ṣaisan (ti o ba sin, tabi o nwukọ, tabi aya di dun pelu itan irin-ajo si eyikeyi ninu awon ilu to ni ajakale arun yi) fi aṣọ inuju bo ẹnu rẹ ki o si sọ fun awọn eleto ilera **NCDC nipa pipe ero ibanisoro ofe: 07032864444 or 080097000010**



### Nigba wo ni o ye ki eniyan wa itoju ni ile iwosan?

1. Wa itọju ilera ni kia kia ni kete ti o ba ni iba, ikọ, iṣoro lati mi irora ati aya di dun
2. Ti ẹnikan ti o wa nitosi rẹ bani eyikeyi ninu awon ami ti a ti menu ba yi, pe  ajo ti o fa fun idena ajakale arun yin i kia kia(**NCDC nipa pipe ero ibanisoro ofe: 07032864444 or 080097000010)**

Printing of this fact sheet is supported by the European Union funded and UNODC implemented project

EUROPEAN UNION

UNODC United Nations Office on Drugs and Crime

**Response to Drugs and Related Organised Crime in Nigeria**